# IṢẸ TI A RÁN SI AWỌN ỌDỌ

**Oniwasu 11:9, 10; 12:1-14**

**ẸKỌ 378 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Opin gbogbo ọ̀rọ na ti a gbọ́ ni pe: Bẹ̀ru Ọlọrun ki o si pa ofin rẹ̀ mọ́: nitori eyi ni fun gbogbo enia. Nitoripe Ọlọrun yio mu olukuluku iṣẹ wa sinu idajọ, ati olukuluku ohun ikọkọ, ibã ṣe rere, ibã ṣe buburu" (Oniwasu 12:13, 14).**

**I Imọran Ti O Dara**

1 Igba ewe gbọdọ jẹ́ akoko ayọ, ṣugbọn kò gbọdọ jẹ́ akoko aṣeju ati ẹṣẹ didá, Oniwasu 11:9, 10; Orin Dafidi 119:9; 1 Peteru 4:3-5

2 Ayọ̀ ti o tobi ju lọ fun ọ̀dọ́ ni lati ranti Ẹlẹda rẹ̀, Oniwasu 12:1; Matteu 18:1-4; Marku 10:14, 15

**II Fun Afiyesi**

1 Igbesi-ayé maa n di ẹrù fun arugbo ati awọn ti ara n ni, Oniwasu 12:1-4; Jobu 3:20-22; Jona 4:8

2 Nikẹyin eniyan ni lati lọ si "ile rẹ̀ pipẹ," Oniwasu 12:5-7; 8:8; 2 Samuẹli 14:14; Heberu 9:27

**III Ọrọ Ikẹyin**

1 Oniwaasu naa n fẹ́ kọ́ awọn eniyan, Oniwasu 12:8-12; Jobu 28:28; Hosea 14:9; Johannu 20:30, 31

2 Gbogbo ojuṣe eniyan ni: "Bẹ̀ru Ọlọrun ki o si pa ofin rẹ̀ mọ́," Oniwasu 12:13; Matteu 10:28; Luku 10:25-28; 1 Peteru 2:17

3 Idajọ Ọlọrun yoo dán ọkọọkan iṣẹ olukuluku eniyan wò, Oniwasu 11:9; 12:14; Orin Dafidi 62:12; Jeremiah 17:10; Matteu 16:27; Ifihan 20:12

## ALAYE

Lẹyin igba ti o ti sá ire ije ayé ti o si ti ri iriri ayé dé ògógoro, Oniwaasu fi iwe akọsilẹ yii silẹ fun awọn ọdọ. Nipa imisi Ẹmi Mimọ, eyi ti a ṣe akọsilẹ rẹ̀ ninu Ọrọ Ọlọrun, iṣẹ́ naa jẹ́ itọni fun gbogbo awọn ọdọ ti n rin ipa ọ̀na ayé yii.

**Si awọn Ọdọ**

Oniwaasu mọ pe bi apakan igbesi-ayé eniyan ba jẹ́ igba ayọ̀, akokò ọdọ ni. Akokò yii jẹ́ igba idunnu, igba ti kò si ohun ti o de ni mọlẹ ati igba ayọ̀. Oniwaasu kò bu ẹ̀tẹ́ lu igba ọdọ, ki i si ṣe pe o fẹ pa wọn laya dà pe ki wọn ki o máṣe jẹ igbadun ti o tọ́. Oun kò si wi pe o yẹ ki awọn ọdọ maa gbé gẹgẹ bi àgba. "Mã yọ̀, iwọ ọdọmọde ninu ewe rẹ; ki o si jẹ ki ọkàn rẹ ki o mu ọ laraya li ọjọ ewe rẹ, ki o si ma rin nipa ọ̀na ọkàn rẹ ati nipa iri oju rẹ."

Eyi ha le jẹ imọran rere? A ha le gbẹkẹle ọdọ to bẹẹ? Gẹgẹ bi aabo Oniwaasu fi idalẹkun yii kun un pe, "Ṣugbọn iwọ mọ̀ eyi pe, nitori nkan wọnyi Ọlọrun yio mu ọ wá si idajọ." Ọna ti ọdọ ba fi ọkàn si lati tọ̀ ni yoo fi hàn boya a le gbẹkẹle iṣe rẹ̀. "Nibiti iṣura nyin bá gbé wà, nibẹ̀ li ọkàn nyin yio gbé wà pẹlu" (Matteu 6:21). Nigba ti ọkàn eniyan ba ṣe deedee pẹlu Ọlọrun, awọn ifẹ rẹ yoo wà lori awọn nnkan ti n bẹ loke, awọn ero ati iṣe rẹ̀ yoo rekọja ariwisi (Ka Galatia 5:22, 23). Awọn ẹni ti Ọlọrun ti rà pada ki i bẹru nitori idajọ Ọlọrun, nitori iṣẹ rere yoo mu ẹsan rere wá. Ọdọmọde ti o ba tori ifẹ ẹ̀ṣẹ tọ ọ̀na iparun yẹ ki o bẹru nitori ẹ̀ṣẹ rẹ̀ yoo tẹle e lọ sinu idajọ.

**Ikorita**

Awọn ọdọ ki i rin pẹ loju ọ̀na ayé ki wọn to de ikorita. Ni apa osi ni ọna gbooro wà ti o n dán ti o si lẹwa ti o si kun fun ọ̀pọ ileri asán. Bi a ba yọju lati wo ẹnu ọna naa, a le ri i pe ọ̀na gbooro kún fún oriṣiriṣi idarayá, igbadun, ohun asán ati ẹ̀tàn. Bi eniyan ba kọkọ ri ọ̀na gbooro, o dabi ẹni pe o rọrun lati rin, nitori o lọ gẹrẹgẹrẹ si isalẹ, kò si gba lilo agbara pupọ lati rin. Ogunlọgọ eniyan ni o n rọ́ wọ ẹnu ọ̀na gbooro ti wọn si n mu ki ọ̀na gbooro kún. Awọn eniyan ti kò tete pinnu boya ki wọn gba ọ̀na gbooro ni eṣu n dán wò, tanjẹ, tì, tabi fa lọ si ọ̀na naa; nitori eṣu ni ọmọ-alade ati alaṣẹ ọ̀na naa, oun a si

ni ọ̀pọ eniyan niwọn bi o ba ti le ṣeeṣe fun un. Ṣugbọn ṣọra! Nitori ikú ati iparun ayeraye ni ọ̀na yii lọ sí.

Ni ọwọ ọtun ni oju ọ̀na kekere kan wà boya eyi ti awọn eniyan ki i ṣe akiyesi lakọkọ. Bi o tilẹ jẹ pe oju ọ̀na tooro kò ni ẹwa ti o le fani mọra to bẹẹ, sibẹ iyebiye ni nnkan ti a fi ṣe e. “Nitori Ọlọrun fẹ araiye tobẹ̃ gẹ, ti o fi Ọmọ bibi rẹ̀ kanṣoṣo funni, ki ẹnikẹni ti o ba gbà a gbọ́ má bà ṣegbé, ṣugbọn ki o le ni iye ainipẹkun” (Johannu 3:16). Bi a ba wo lati ẹnu ọ̀na iyanu yii, a o ri ọ̀na tooro. Ọna ti o gba oke ni, o si daju pe ó gba agbára lati rin nibẹ. Ọpọ inudidun ati igbadun tootọ wa loju ọ̀na yii pẹlu ṣugbọn wọn kò ṣe e ri fun awọn ero-woran ṣá. Ero kò pọ̀ loju ọ̀na naa nitori iba eniyan diẹ ni o n bá ẹnu ọ̀na tooro naa wọle. A kò mu ẹnikẹni nipá lati rin ọ̀na yii ṣugbọn gbogbo eniyan ni Ohùn Ẹnikan ti o duro ti o si n kan ilẹkun ọkàn gbogbo ẹda n pè. Feti si Ohùn naa! Feti si ipe Ẹmi ki o si wọ ẹnu ọ̀na tooro naa nitori ọ̀na tooro naa lọ si Ọrun ati iye ainipẹkun!

**Ipinnu Pataki**

Ọna wo ni iwọ yoo gbà? Olukuluku ni yoo ṣe ipinnu yii fun ara rẹ̀, ṣugbọn dandan ni, a gbọdọ ṣe e. Erò kin-in-ni ti o kọkọ maa n wá si ẹni ti ọkàn rẹ̀ sọji ni lati fà sẹyin lati ṣe ipinnu; ṣugbọn Ọlọrun n kan otitọ mọ́ àya olukuluku pe ifasẹyin jẹ́ ipinnu si ọ̀na odi. Oniwaasu mọ ọ̀na igbesi-ayé mejeeji naa daju, o si rọ awọn ọdọ lati yan ọ̀na ti o tọ́ nigba ti wọ́n wà ni ewe.

Awọn ọdọ maa n bẹrẹ igbesi-ayé wọn pẹlu ẹri-ọkan rere eyi ti bi wọn ba fi tọkantọkan tẹle, yoo mu wọn de ọdọ Ọlọrun. Ni igba pupọ ọ̀na ti kò tọ́ ni wọn n ṣe akiyesi ti wọn si n tẹle. Lai pẹ́ wọn a bẹrẹ si ni iwa ti wọn. Iṣe kan, gẹgẹ bi fọnran owu alantakun, a maa fa ekeji mọra. Iwa buburu kan maa n ti ni si omiran, ekeji a si maa n rọrun ju igba ekinni lọ. Ọkunrin kan la ọ̀na kọja lori yinyin pẹlu iṣoro lọwọ aarọ kutukutu, ṣugbọn bi o ti n rin lori rẹ̀ nigbakuugba ni yoo maa gbooro si i ti yoo si maa rọrun si i lati rin. Gẹgẹ bi akiyesi, iwa tabi iṣe ti eniyan bá bá di ọmọ ọdún mẹẹdọgbọn tabi ọgbọ̀n ọdún ni yoo ba a dagba. Gẹgẹ bi irin tutu ti n di yiyọ ninu ina ileru ti o si n ṣan bẹẹ ni igba ọdọ kò ṣoro lati tẹ̀ si nnkan tabi fi ara mọ́ nnkan. Ṣugbọn lai pẹ, irin ti o ti mú aworán ohun ti a yọ ọ si, yoo di tutu, a si le koko. Bẹẹ gẹgẹ ni iwa ti o ba ti di ara fun ọdọ maa n ṣoro lati gbà kuro.

**Aini Ọlọrun Nigba Ogbó**

Nitori pe gbogbo nnkan wọnyii jẹ́ otitọ, kò ya ni lẹnu pe Oniwaasu ké si gbogbo awọn ọdọ pe: “Ranti ẹlẹda rẹ nisisiyi li ọjọ ewe rẹ, nigbati ọjọ ibi kò ti ide, ati ti ọdun kò ti isunmọ etile, nigbati iwọ o wipe, emi kò ni inudidun ninu wọn.” O tẹ̀ siwaju nipa fifun ni ni apẹẹrẹ ọkunrin arugbo kan ti o ti lo gbogbo ọjọ́ ayé rẹ̀ lai sin Ọlọrun, o si n reti pé ki ikú mu oun lọ kuro ni ilẹ alaaye. Lai si aniani ọkunrin yii gẹgẹ bi ogunlọgọ awọn eniyan miiran, pẹlu ti gbọ́ ipe Ọlọrun si ododo ni igba kan, o ni ipinnu lati sin Ọlọrun ni ọjọ iwaju, ṣugbọn nisisiyii ọ̀ran naa ti kọja eyi ti o tun le maa ṣe aniyan nipa irú nnkan nla bayii.

Gbogbo ọjọ ogbó ọkunrin yii ni o kún fún òkunkun; kò si oorun, oṣupa tabi irawọ lati fi imọlẹ si ayé rẹ̀. Agbara nipa ti ẹda ti lọ, oju ti di baibai, ounjẹ kò mu igbadun wá mọ́ nitori pe eyin kò pọ̀ ni ẹnu mọ́, ounjẹ kò si dà ninu to bẹẹ mọ́; agbára kaka ni eti si fi n gbọran; ailesun ti di igba gbogbo; ibi giga si ti di ẹ̀ru.

Ọjọ ikú n sunmọ etile, awọn aṣọfọ ti n banujẹ nitori ikú ti n bọ̀, n rin jẹjẹ laaarin igboro. Ikú dé -- ọkunrin naa si lọ si “ile rẹ̀ pipẹ.” Erupẹ si pada si ilẹ bi ti o ti wà ri, ẹmi si pada tọ Ọlọrun ti o fi funni, ki a le ṣe idajọ rẹ̀ gẹgẹ bi iṣẹ ti o ṣe ninu ara. Ni ọnà kan bi a ba ṣe aṣaro le itumọ ọrọ Oniwaasu, a o ri ọ̀rọ ibanujẹ ati ikilọ ninu rẹ̀. Bi o ba ṣe pe ọkunrin arugbo naa ti wá Ọlọrun nigba ewe rẹ̀ ni, ti o si ti sin In ni gbogbo ọjọ ayé rẹ̀, ọjọ ikẹyin rẹ̀ lori ilẹ ayé i ba ti pari ni ayọ̀ ju bayii lọ.

**Ninu Kristi**

Ẹkọ ti Ẹmi n kọ́ ewe ati àgba ni pe ikú ki i ṣe ohun ẹ̀ru ati ibanujẹ fun awọn ẹni iwa-bi-Ọlọrun. A le ṣe atunwi ọ̀rọ otitọ yii pe ẹni ti o ba gbé igbesi-ayé rere, yoo kú ’re, i ba a ṣe ọmọde tabi àgba. Nitori ti Oniwaasu ti ri iriri imulẹmofo ayé, o si ti ni oye eyi ti i ṣe igbesi-ayé rere, nitori naa o n gba gbogbo eniyan ni imọran pe ki wọn ki o gbé igbesi-ayé rere. O kọ́ awọn eniyan ni imọ̀, o si kọ ọ̀rọ otitọ ti o le fi

ẹsẹ̀ eniyan mulẹ. Bi a ba lo o ni ọ̀na taara, Ọrọ naa ti o kún fún imisi Ọlọrun yoo pa arinrin-ajo lọ si Ọrun mọ́ yoo si fi ẹsẹ̀ rẹ̀ mulẹ ni ọ̀na Otitọ.

Ninu awọn ohun ti o jẹ́ iyanu ninu ayé yii ni lati ri agbalagba ti o ni iriri igbagbọ́ ninu Jesu Kristi. Agbára ẹya ara rẹ̀ le ti yẹ̀ gẹgẹ bi a ti ṣe apẹẹrẹ rẹ̀ ni iṣaaju, ṣugbọn igbesi-ayé rẹ ki i ṣe asán. Ireti ati wà pẹlu Oluwa rẹ̀ lai pẹ a maa fi ayọ̀ sinu igbesi-ayé rẹ̀. “Lati wà lãye jẹ Kristi, lati kú, jẹ ere” (Filippi 1:21). Ikú ki i ṣe ẹ̀ru fun awọn ẹni diduro ṣinṣin: “Ikú, oró rẹ dà? Isà okú, iṣẹgun rẹ dà? … ọpẹ́ ni fun Ọlọrun ẹniti o fi iṣẹgun fun wa nipa Oluwa wa Jesu Kristi” (1 Kọrinti 15:55, 57).

**Opin**

A mú ọ̀rọ iwe yii wá si opin nipa sisọ bi o ti jẹ mọ wa. “Opin gbogbo ọ̀rọ naa ti a gbọ́ ni pe: Bẹ̀ru Ọlọrun ki o si pa ofin rẹ̀ mọ́: nitori eyi ni fun gbogbo enia.” “Bẹ̀ru Ọlọrun,” eyi ni pe bọla fun Ọlọrun ki o si sin In. Eyi ni gbogbo iṣẹ eniyan -- iṣẹ kin-in-ni ti o ṣe pataki ti eniyan gbọdọ boju to. Boya eniyan lọrọ tabi o ṣe alaini, o ṣe ẹni giga tabi ẹni ti o rẹlẹ ni ero ti eniyan, kò jẹ́ nnkan nitori awọn nnkan wọnyii yoo kọja lọ. Awọn iṣura iwa-bi-Ọlọrun ninu ọkàn ọmọ-eniyan yoo wà titi ayeraye.

Lati fi idi ipinnu lati jẹ́ ẹni iwa-bi-Ọlọrun mulẹ, Oniwaasu tun sọ otitọ idajọ siwaju si i: “Nitoripe Ọlọrun yio mu olukuluku iṣẹ wa sinu idajọ, ati olukuluku ohun ikọkọ, ibã ṣe rere, ibã ṣe buburu.” Bi awọn ọ̀rọ kan bá wà ti o le mu oye eniyan wá sile, awọn ọ̀rọ yii tó. Lati jingiri sinu ẹ̀ṣẹ jẹ́ isinwin ti ẹmi. Ọdọmọde lọkunrin tabi lobinrin ti ori rẹ̀ pé, ti o si ni imọ̀ daju nipa idajọ Ọlọrun ati igbẹyin eniyan buburu kò le ni ipinnu miiran yatọ si akojọ ọrọ Oniwaasu ti o wi pe, “Bẹ̀ru Ọlọrun ki o si pa ofin rẹ̀ mọ́: nitori eyi ni fun gbogbo enia.” Akoko yii gan an ni a gbọdọ ṣe ohun ti o tọ́; akoko yii ni igba ti o yẹ lati tẹle Jesu Kristi bi o ba ṣe pe eyi ki i ṣe ọ̀na ti iwọ n tọ̀ tẹlẹ ri.

## AWỌN IBEERE

1 Imọran wo ni Oniwaasu fun awọn ọdọ?

2 Idabu wo ni a fi si ilepa awọn ọdọ?

3 Ki ni ṣe ti o fi yẹ lati ranti Ẹlẹda ni igba ọdọ?

4 Ki ni ṣe ti a fi n tọka si ikú bi “ile pipẹ” ti ọmọ eniyan?

5 Nibo ni ara ati ẹmi n lọ ni akoko ikú?

6 Sọ orişirişi ọ̀na ti Oniwaasu gbà lati fi imọran kọ́ awọn eniyan.

7 Ki ni opin ọ̀rọ ti a sọ ninu ẹkọ yii nipa gbogbo iṣẹ eniyan?

8 Ofin Ọlọrun wo ni o fi idi ọ̀rọ yii mulẹ?